# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 716 THURSDAY JUNE 11, 1964 (2D)


## Okunrin Kan Bę Sinu Odo Osa

EKO:- Idamu nla ba gbogbo enia ti nwon wa ni tosi nigbati Okunrin kan, eni odun mejdelogbon ti o si gun ni ese bata mefa sare jade lati ile iwosan EKO ti o si bę sinu odo Osa ni ojo Aje ti işe ojo kejo oşu yi.

Lesekese ni gbogbo awon oşişe ile iwosan na ti sare jade ti nwon si ranşe si awon Olopa pe ki nwon tete ma sare bo wa si Marina niwaju ile iwosan Eko, şubon ki awon Olopa na to de awon enia to wa ni tosi bo ewu won silę nwon si wo inu odo osa lati yo Okunrin na jade

Enlti oro na se oju re fi ye onirohin wa pe inu kan lo nyo iyawo arakunrin na lenu osi sare gbe wa si ile-iwosan fun itoju. Şugbon nigbati iyawo na ko gbadun ni awon Dokita ba şişe fun ni ojo abameta ti işe ojo Abameta ti işe ojo keta oşu yi nigbati odi ojo keji ti nwon sişe obe fun tan ni obinrin ba ku.

Şugbon nigbati oko re şiwo kuro ni bi işe tan ko mo ohun ti Oşelo si iya wo re ni ile iwosan ko ti dele ti o fi sare lo lati lo wo alafia iyawo re, bi o ti de ile iwosan oku iyawo re loba ni le ti awon Dokita ntoju re nwon si so fun pe "Iyawo re ti ku".

Okunrin yi ko mo bi aiye ni on wa bi Orun ni are lo sa jade ni ile iwosan to si bę sinu odo-osa ki awon oşişe ile iwosan na to sare wa yo jade. Okunrin na wa ni itoju awon Olopa nisisiyi pe ki o turaka ki o ma se banu je.

# OKE MARUN (100, 000) AWON OLUKO DAŞE SILĘ

EKO:— Gbogbo awon Omo ile iwe jakejado ile Naijiria ni nwon bere si da kiri bi agutan ti ko ni Oluşo nigbati nwon de ile iwe won ni kutukutu Owuro ana ni Ojo ru ti nwon ko si ba Oluko kankan ni ile iwe ni awon na ba bere si şere kakiri inu ogba ati kakiri gbogbo ilu.



Aworan oke yi ni ti awon Oşişe ti nwon da işe silę

Ninu ipade kan ti awon Oluko na şe ninu ile iwe St Judes loru ana gbogbo awon Oluko na ni nwon pinnu pe bi awon ba de ile iwe awon ni oni awon ko ni şişe kankan awon yio si joko sibe ma wo awon Omo niran.

Agborosọ awon oluko na şe alaye fun oniwe irohin wa pe ekunwo owo oşu eyi ti igbimo Oluwadi Morgan palaşe pe ki ijoba san fun awon Oşişe ti ijoba si ko lati san fun won on na lo ndun awon lokan ti awon si pinnu lati da işe silę.

Agborosọ na tun şe alaye siwaju ninu oro re pe. "Bi ijoba ko ba san ekunwo owo-Oşu na fun wa, ko si eniti yio pada senu işe ninu wa" ki ipade na to pari awon Oluko na fi iwe-egbe won ranşe si ile işe Minista alamojuto eto eko fun ijoba apapo ilę Naijiria pe, a fun wakati merinlelogun pere ki o fi so fun wa pe apapo ijoba yio san owo na fun awon Oluko tabi ko ni san.

Bi apapo Ijoba yio ba san ekunwo owo osu na ki Minista alamojuto eto eko tete so fun won larin wakati merinlelogun yi bi awon ko ba si ri iwe re titi di asiko ti awon da yi, gbogbo awon yio da işe silę.

Ogbeni E. E. Esua ti işe akowe Igbimo egbe aluko fun gbogbo Naijiria dide lati soro ninu ipade ti nwon şe yi şugbon awon Oluko ko gba laye lati soro.

Bi o ti dide lati soro beni okan ninu awon oluko na şe alatako re pe, "Akowe e lo wa bi kan joko si nbo lo ti wa lati ojo yi tabi bi gbogbo nkan ti nlo lati ojo yi o ma so fun wa pe o gbo? ti o ba fe gba abuku ki o ya sare jade nisisiyi kiakia."

Bi okunrin yi ti soro tan ni gbogbo awon oluko ba ho bo akowe na pe, "Akowe ko wura e lo wa bi kan joko si wayi" şugbon bi nwon ti nsoro yi lowo Ogbeni M. J. Etuk ni okan ninu awon olori egbe awon oluko ba sare dide ti o si so pe, "Mo fe ki ogbeni Esua wa larin ijoko wa yi, bi o tile je pe eo ni gba laye lati soro"

Mo mo daju pe gbogbo yin ni oro ekunwo owo-oşu yi ndun lokan ti e si ti pinnu lokan yin lati da işe sile. şugbon e ma gbagbe pelepele ni a le fi yanju oro yi gegebi ati je eniti nko gbogbo aiye. A si gbodo fi apere re re lele eyi ti yio je ape re fun awon elomiran lati tele

Nitorina, e je ki Ogbeni Esua wa ninu ipade wa yi lesekeso ni gbogbo won si dake laikosi alatako titi nwon fi pari ipade won na.

Titi ti nwon fi pari ipade na ni Ogbeni Esua joko je e lori aga şugbon nwon ka gbaa laye lati soro

Ki ipade na to pari nwon so pe ki awon fi ipinnu ti awon şe ninu ipade na ranşe si ile işe minista alamojuto eto eko fun apapo ijoba ilę Naijiria pe awon fe ekunwo owo-oşu eyiti igbimo Oluwadi Morgan palaşe pe ki apapo ijoba Naijiria san fun awon Oşişe.

Ni ipari awon oluko na ni, ki ile işe alamojuto eto eko tete so ipinnu re fun awon ninu eto oro na bi apa po ijoba yio san owo na fun awon tabi ko ni san,

Igbimo awon oluko na wa pari oro won pe, "A fun minista alamojuto eto eko apapo Ijoba Naijiria ni wakati merilelogun pere lati so ero okan re lori oro yi bi a ko ba si ri esi oro yi titi di asiko ti a da yi gbogbo awa oluko ni a o da işe wa silę ti a ko si ni ko awon omo ni eko won mo",

Şugbon titi di asiko ti a fi nko iwe yi loru ana ile işe Minista alamojuto eto eko ko ti da esi iwe won pada asiko ti awon Oluko da si ti koja ni gbogbo won ba şe da işe silę ni owuro ana.

Awon omo ile iwe bere si şire kakiri ilu awon miran şire lo sokun, awon miran şire lo si ori kereni Iddo, awon miran şire lo si arin oja, nigbati asiko ijade ile iwe to gbogbo won si pada wa sile.

Irohin fi ye wa pe oke marun odin egbedogun (97, 000) enia ni gbogbo awon Oluko to wa ni Eko ati agbegbe re nikan gbogbo won ko si ti da işe silę a lero pe bi awon omo ba lo si ile eko ni owuro yi ko si Oluko lati ko won.

„Awon omo ile iwe gba holude tulasi"

# IWE SI OLOTU

## Mo Ki Ọgbẹni Ẹdẹt

Olotu, jọwọ gba mi laye ninu iwe Irohin rẹ oloyin mọmọ, ti nkọ gbogbo enia ni ọgbọn ati oye ti ko ni abawọn' lati ki ọgbẹni Ẹdẹt ti iṣe Ọga- Agba awọn ọlọpa fun ọna ti ogba ti o fi din iwa ojukokoro ati owo ẹhin gbigba kun ni orilẹ-ede yi,

Eyi jẹ iwa ti o dara ati ibẹrẹ iṣẹ ola fun Ọga awọn Ọlọpa ni Naijiria.

Ṣugbọn o yẹ ki awọn oniwe Irohin sowọpọ pẹlu Ọgbẹni Ẹdẹt lati ma fun awọn ara ilu ni ojulowo imọran nipa Iwa buruku yi, ojukokoro ati owo ẹhin gbigba.

Babakanna ni awọn olori wa ati awọn oṣiṣẹ Ijọba nihin gbọdọ mọ pe owo ẹhin gbigba ko dara.

Lakotan ọrọ mi yi, oyẹ ki gbogbo wa mọ pe owo ẹhin ko dara ki mu ilu ti oba jọba ninu iwa yi ni ilọsiwaju nitorina odi ọwọ wa Ẹku iṣẹ o.

Emi ni
Latifu Babalọla
EKO.

## Ikorodu Nkọ?

Mba ṣọpẹ bi Olotu bale gba mi laye lati kesi awọn alaṣẹ ile-Iṣẹ Ina mọnamana E, C. N. lati lo aye wọn rere yi lati ṣi ile-iṣẹ wọn si ilu Ikorodu.

Nitori ọma ngba wa ni a koko ju ki ato le san owo ina ati aba jẹ paapa wahala lo jẹ fun wa lọpọlọpọ ki a to lọsan owo ina wa nitori ilu Ṣhagamu ni a ti nlọ san owo ina.

Ni idi eyi inu wa yio dun pupọ ti awọn alaṣẹ ile-iṣẹ yi ba le ṣi ẹka ile iṣẹ wọn si Ikorodu ati Igbogbo ki ole jẹ Irọrun wa lati ma san gbese wọn fun nwọn ni asiko.

Inu wa yio dun pupọ bi ẹ ba tete ba wa ṣe eyi

Emi ni
Afọlabi Amusa
IKORODU

## Ẹ Fun Wa Ni Ina

Inu mi ba dun pupọ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye ninu iwe rẹ aladun lati kesi Ijọba Apapọ ki nwọn fun wa ni Ina ilẹntriki ni awọn adugbo nwọn yi, Ayilara, Surulere,

Nitorina a bẹ awọn alaṣe ile-Iṣẹ E. C. N. lati fun awọn adugbo yi ni ina, nitori ti o ba di ni alẹ okunkun ni adugbo na ma wa, eleyi si le fa nkan buruku fun adugbo na papa awọn ọmọ Jaguda yio tete ma ri aye sisẹ buruku nwọn. Inu awa olugbe adugbo na yio dun bi Ijọba ba tete ba wa ṣe eyi.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, Iwaju ni ọpa ebiti nyin yio ma re si o.

Emi ni,
Sunday Adelọwọ
SURULERE.

## Ẹ yan Olupo Ni Asoju

Mba ṣọpẹ bi olotu Irohin-Imọlẹ ba le gbami laye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa paapa Gomina Ipinlẹ na ki o lo aye rẹ rere yi lati yan oloye Fọlayan Olupo ti Ilu Ajasẹpo si Ile Igbimọ awọn Ọba ti Ipinlẹ Ariwa.

Gẹgẹbi itan tiso fun wa ninu awọn Ọba ti Ilẹ Igbomina Olupo jẹ ọkan pataki ti a si bọwọ fun julọ ni arin awọn Oba Ilẹ na lati ọjọ yi wa ko ti si Ọba kan ni Ilẹ Igbomina ti o nṣoju ilẹ na ni Ile Igbimọ awọn lọbalọba ni Ipinlẹ Ariwa.

Nitorina inu awọn Ọmọ Igbona yio dun ti ẹ ba le yan Oba Olupo lati Ajassẹ lati jẹ asoju wa ni ile Igbimọ lọbalọba.

A bẹ Alhaji Ahmadu Bello lati tete ba wa ṣe ẹdun ọkan wa yi fun iṣẹ ati alafia ilẹ Naijiria, nitori ọkan na ni gbogbo wa.

Emi ni
Sedu Olupo
Ajassẹ ipo

## Itan Ilu Ajiran Dun

Inu mi yio dun pupọ gidigidi ti ẹ ba gba mi laye lati ba Ọgbẹni J. O. Shoyinka sọrọ ninu iwe yin oloyinmọmọ (Irohin Imọlẹ)

Ọrọ ti mo fẹ ba Ọgbẹni J. O. Shoyinka sọ ni wipe mo dupẹ lọwọ rẹ pupọ fun ti Itan AJIRAN ILU AWỌN OKU ti o kọ lẹsẹsẹ sinu iwe Irohin yi. O jẹ itan ti o fun ni ni imọ ati oye.

Ṣugbọn fun anfani wa ati ti



Ọgbẹni J .O Shoyinka

awọn ọmọ wa ti wọn nlọ si ile-ẹkọ, o wu mi ki Ọgbẹni J. O. Shoyinka ṣe itan na sinu iwe kekere fun tita nitori ọjọ iwaju, Eyi yio ṣe tọju sọwọ.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni,
L. Ọla Noah
MUSHIN.


## CLASSIFIED ADVT

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egobgi awọn Faranse gidi ti a npe ni

**'CORSIVER'S**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹra u tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ihadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹru ibiṣibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn anodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos,
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KOWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wa we lẹrkansoso ko ri iyato

# Asinwin Ni Ọmuti

Lati Ọwọ:- ALHAJI AWAIYEWAṢERE, Eko

Ọti amupara, a ma a ti enia ni, Laakaye ọmuti ki i pe, Ifun ọmuti a ma a sorikodo ni, Ẹni ti o ba ngmu ọti amu para, a ma a sọ isọkusọ, A si ma da aba lati ṣe ohun ti ko ni agbara rẹ rara. Yio si ma a ṣe ileri pe, on le sọ oke di ilẹ, Ko si ọmọ enia kan lori ilẹ aiye ti a mbẹ ninu rẹ yi ti o nfi ọti mumu, a ni ọti amupara ṣe ayọ ti igbesi-aiye ko ni bajẹ mọọlori gbogbo ohun ti o ba ti kọja aala, ki yọri si rere.

Ọlọrun ko fẹ aṣeju. Aṣeju ni baba ẹtẹ, Alaseju ki i gba iyi. Ẹni ti o ba nka ọrọ ọmuti si, o ntan ara rẹ jẹ ni Ẹni ti ọ ba nka ọrọ ọmuti si, o nda ara rẹ laamu ni Ohun ti ọmuti ba sọ nigba ti o ba ti mu ọti kọja aala ko si ni kaakun mọ nigbati esi ọti ba ti kakuro loju rẹ, Ọmuti ma a ngbagbe iṣẹ rẹ ni, Ọmuti fẹran ọti ju onjẹ gidi lọ, Ọmuti ni ifẹ si ọti ju ẹṣọ ti o dara ti o si fuyi lọ. Ọmuti fẹran ọti ju ile lọ, Ọmuti ngbe aṣọ rẹ ta nitori ki o ba le ri owo ti fi mu ọti, Ọmuti ngbe ohun ini rẹ bi wura ta lati le ri owo fi mu ọti idi niyi ti awọn ọlọgbọn ati awọn oni laakaye fi nkọọ lorin lati igba IWAṢẸ pe, "Ọmuti gbagbe iṣẹ rẹ".

Mo si bẹ ẹnyin ọdọ ile iwe pupọ. Mo si bẹ ẹyin ọdọmọde kunrin ati ọdọmọdebinrin ti ẹ wa lẹnu iṣẹ pe, ki ẹ maṣe kaṣa ọmiti, ki ẹ maṣe kaṣa ọti mimu. Ki iṣe aṣa ire, aṣa iparun ni o jẹ. Aṣa ṣu ni o jẹ. Awọn ọmuti a ma a gbe ogun ti ara wọn nigbati ọti ba tan ina si wọn loju: Lori ọrọ kekere ni nwọn yio si fi gbe ogun ti ara wọn. Awọn enia gidi, awọn bi Ọlọla Dọkita Tẹsilimi Ọlawale Elias, Oloye Aminu Kosọkọ, Alufa Atilade, Hadji Imam Agba-Liadi brahim ati Hadji Imam A W Jẹnmi konra ọti, nwọn si konra ọmuti Mo bẹ ẹyin ọmuti, ẹ lọ ronupiwada, ki ẹ si jawọ kuro ninn eepo ẹpa ti ko ni ọmọ ninu, Ki ẹ jawọ kuro ninu owo adanu, Ki Edumare ṣe amọna wa o, Bi ọmuti ba pe ẹ ni were, maṣe binu. Ki iwọ si mọpe, on ni asinwin, ti laakaye rẹ si ti dorikodo Oju ko fẹraku o

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Ere nla kan mbẹ niwaju fun ọ, mase fi ọkan balẹ si nitoripe ileri na le yẹ ọjọ Saturday ni ọjọ orire rẹ awọn enia yio si ma jowu rẹ ni ti paapa.

ARIES (Feb 21-Mar 20) Ẹnikan yio ṣe ju o lọ ninu ẹgbẹ kan ti o sẹṣẹ wọ, ṣugbọn bi o tun raṣe, iwọ yio ni ilọsiwaju.

PISCES (Mar 21-April 20) Nipa ayipada ti iwọ yio ṣe, ni yio sun ọ lọ gbe abule kan, ti o wa nitosi ibiti o ti ngbe. Idalẹ ti o lọ na, mase pẹju ki nwọn mase sare wa pe ọ nile.

TAURUS (April 21-May 20) Awọn obinrin ni gbogbo ti o nse idina fun ọ nigba gbogbo, bi o ko ba mura ki o gbara rẹ silẹ lọwọ wọn, ẹhin igba lo nyin agbado si, Adanwo na yio tagun diẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Ọrẹ rẹ kan yio gbe ọ sinu mọto yi de lọ maṣe ṣare rẹ ni pantiri, Ọkunrin alagba kan ni yio yọọ jade kuro ninu jamba ti o ma ko si na, Maṣe alaimore si Okunrin na

CANCER (June 22-July 22) Ọjọ Saturday ati Ọjọ Sunday yio dun fun ọ pupọ ma reti irohin ayọ kan lati ọdọ ẹbi ti o nreti ọjọ ti iwọ o pada wa sile, maṣe wahala nipa ọrọ ti o ko mọdi

LEO (July 23-Aug 22) Ọjọ oni Ọja rẹ yio taju jẹki Ọgbọn ori rẹ pe owo yio tẹ ọ lọwọ jaburata laipẹ, ṣugbọn maṣe ya ẹni kan ni owo atisan owo pada yio di eti nişişi bayi, ọrẹ a si bajẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ohun rere kan nfẹ ṣẹlẹ si ọ Iwọ yio ri owo ko jọ ati dukia pupọ okiki rẹ yio si kan lọdọ awọn aladugbọ rẹ maṣe ba ẹni kan ṣe apapọ ki dukia rẹ mase bajẹ

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Iwọ yio ṣe orire lọpọlọpọ ni ọjọ saturday, ṣugbọn lọsan ọjọ na bukata pupọ yio ṣe si ọ, maṣe ni awọn ẹlẹgbẹ rẹ sinu.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Rọra ma tẹ siwaju diẹdiẹ, ki o fi alamọri ti awọn ọmọ rẹ si ero, ṣọra ninu ọ ṣe yi nitori iwọ yio ri ohun ibinu maṣa binu.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ṣọra pupọ nitori iṣekuṣe kan ti iwọ yio ṣe lọjọ sunday, iṣekuṣe na le ṣe ifasehin fun ọ. Iwọ yio ṣẹgun nigbẹhin.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Maṣe ba ẹnikan diẹ pọ nitoripe bi o ba bẹ silẹ ko ni bimọ rere.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI- Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi şişẹşe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daadaa ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju Bere Egbogi na ni Ṣọbu:a

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji Lagos)
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrinla oṣu yi (14/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Ao si tun ti tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ ki ẹsi tete de.

LATEEF BABALOLA
Akọwe Agba

# Njẹ Balewa Yio Fi Ipo Rẹ Silẹ Fun Ribadu ?

KADUNA:— Laipẹyi ni irohin de ọwọ wa lati Kaduna nibi ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ N. P. C. ṣe eyiti Olotu Ijọba Apapọ, Ọlọla Abubakar ko ba wọn ṣe ati pe Olotu na wa ni ilu rẹ Bauchi nibiti o ti nlo isimi ni a si ti gbọ pe Olotu yio fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Olotu Ijọba Apapọ ti ẹgbẹ nwọn ba le bori ninu ibo ti nwọn yio di si Ile Igbimọ Ijọba Apapọ larin ọdun yi.

Irohin ti ari gbọ lati ẹnu awọn ẹgbẹ na ni pe Ọlọla Abubakar yio lọ simi ninu ọrọ oṣelu Ọlọla Abubakar ni igbakeji Olori ẹgbẹ N P C Ohun ti yio mu ki Ọlọla Abubakar to fẹ fi ipo na silẹ si jẹmọ ọran kan tokọ je akoso rẹ.

Irohin na fi ye wa pe ti o ba fẹ fi simi ninu ọrọ Oṣelu pe ko ni fe pada si ile igbimọ asofin apapọ lesi ko idibo Irohin na tun fi ye wa pe ti Ọlọla Abubakar ba kuro pe,



Alhaji Abubakar Tafawa Balewa
Alakoso Ijọba Apapọ Ilẹ Naijiria

Alhaji Muhammadu Ribadu ni yio gba ipo rẹ gẹgẹbi Olotu ijọba apapọ ti ẹgbẹ nwọn ba wọle idibo si ile igbimọ asofin ijọba apapọ, ti ilẹ Naijiria.

Irohin na tun fi ye wa lati ẹnu awọ. Ọmọ ẹgbẹ N. P. C. pe ki yio si ija rara fun ẹniti o ye lati rọpo Ọlọla Abubakar Olotu Ijọba apapọ ilẹ Naijiria.



Alhaji Ribadu

Irohin na tun fi ye wa pe aṣepọ Ọlọla Abubakar ati Olori egbe N P C, Ọlọla Hamadu Bello ko si ṣe dede mọ lati bi igba diẹ ati pe awọn Ọmọ ẹgbẹ na si ngbiyanju lati dekun si aiṣe dede na ki o ma ba da rogbodiyan silẹ larin ẹgbẹ N. P. C

Fun igba die, awọn ọmọ ẹgbe na si ti pin orilẹ ilẹ Naijiria si ọna marun fun ẹgbẹ N. P. C ati pe nwọn si ti yan ninu awọn olori ẹgbẹ na lati jẹ olori fun apa kọkan.

Olori ẹgbẹ N P C ati Olotu ipinlẹ ariwa ni yio wa gẹgẹbi alabojuto fun ipinlẹ Ariwa Alakoso eto iṣẹ elentiriki fun ijọba Apapọ Alhaji Yesufu Maitama Sule ni yio wa gẹgẹbi alakoso agbegbe Eko. Alakoso eto iṣẹ fun Ijọba apapọ Alhaji Inuwa Wada ni yio wa gẹgẹbi alakoso fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, Alakoso eto aje fun Ijọba apapọ Zanna Bukar Dipcharima ni yio wa gẹgẹbi alakoso ipinlẹ ila Orun ati alakoso fun eto awọn ologun Alhaji Ibrahim Tanko ni yio wa gegebi Alakoso agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun.

## IKEDE

Eto ikede ajumọṣepọ ẹgbẹ N P C pelu ẹgbẹ Dẹmọ (N N D P) yio jade lati ọwọ Alhaji Innua Wada nigbakugba si isiyi.

Ẹgbẹ N P C si ti bu ẹnu ate lu olori ẹgbẹ NEPU Alahaji Aminu Kano fun ọrọ ti o sọ jade laipẹ yi gegebi Ogboju Oselu Awọn ọmọ ẹgbẹ na si tun sọ pe ohun to fa idaduro nipa idi bo si ile igbimọ ibilẹ ti ilu Bauchi pe ki iṣẹ pe aya nwọn ati pe ẹgbẹ NEPU yio bori ninu idibo na gẹgẹ bi Alhaji Aminu Kano ṣe sọ si.

Awọn ọmọ ẹgbẹ N P C si tun sọ pe o da loju yio bori ibo nibe nitori pe awọn enia mọ dada ni agbegbe na.

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirisi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe gbeyawo
TETE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo leeka" soso ko ri iwato

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI- Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi şişeşẹ ti o kọ le jeun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adorin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio b ẹ s'i dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Şọbu:a

ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street, Yaba
WATERLOO MEDICINE STORES
9, Palmchurch Street, Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji Lagos)
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No, 716 THURSDAY, JUNE 11, 1964 (2D)

## Moto Wolu Okunrin Kan Mole

AGEGE:— Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati moto-akero kan baje ti omo ekose moto kan, Ogbeni Audu Gombe, eni odun merindinlogbon bosi abe moto na lati tun se, sugbon bi o ti ntun moto na se ni ese moto na ba tase loke ti nwon gbe si ti o si wolu mole ni ojo Isegun ti ise ojo kesan osu yi.

Onirohin wa ti Oran na soju re fi ye wa pe, taya ese ehin moto na lo fo nwon si fi irinse won gbe moto na soke. Lojukanna na Gonbe ba sare wo abe moto na lo pe ki on yo taya ti o baje kuro, ki on si gbe Omiran si i.

Sugbon bi o ti ko si abe moto na, ti o si yo taya ti o baje jade, ni o ba ni ki on gbe taya miran si i pada. Bi o ti fe gbe taya na si i, ni moto na ba ye kuro lori irin ti nwon gbe moto na le lori, ti o si wolu Gonbe mole.

Lesekese ni gbogbo awon ero Oja Agege ba sare de, ti nwon si wa gbe moto akero na kuro lori Okunrin na. Sugbon nigbati nwon o fi gbe moto na kuro, Okunrin na ti ku bamubamu

Awon Olopa ti gbe oku Okunrin na lo si Ile-iwosan lakulaku fun ayewo, nwon si nse iwadi Oro na lowo.

## Ijoba So Fun Awon Osise Pe:

# Ẹ PADA SI ẸNU IṢẸ NYIN

## Iyawo Dun Losingin, Oko Tun Mi gbe

POTA:— Irohin ko to afojuba ni ti ayeye inawo igbe yawo ti Ogbeni Olu Meleki okan ninu awon Oga Agba ile ise oko oju-omi ati Omidan Omiunu se ni ojo Abameta ti ise ojo kerindinlogun osu karun odun yi.



Ogbeni Olu. Meleki ati Omidan Omiunu

Onirohin wa ni Pota fi ye wa pe lati ojo ti nwon ti nse iyawo, ko si eniti o ti se iru iyawo ti Ogbeni Olu Meleki ati iyawo re se.

Nigbati iyawo ti ku bi ojo marun, ni awon alabaseye ti beresi de lati Mobalufon, Ijebu-Ode, Ibadan, Enugu, Oyo, Jos, Eko ati bebe lo

Nigbati o di ojo igbeyawo gan, ti awon alabaseye beresi jo ilu apanran ati apala, nse ni gbogbo awon Ibo ti o wa ninu ilu na damuso ti nwon si nworan bi awon enia na ti na owo.

Oko Iyawo na na wabi-wosi owo ni ojo na ati Ogbeni Ajayi ti o nsise ni ile itewe "Daily Express" ati Iyaafin Victoria Demuren ati Iyaafin Meleki ti ise iya oko iyawo.

Irohin ojo na ko se ko sinu iwe irohin tan, gbomo kuro lori eni mo fe te nkan a fi en ti yio ba te gbese.

Inawo ojo na kanmomo, o le gongo Awon alabase ye ojo na mu oti ati onje ni ajeti ti o fi di ojo keji, nwon ko mo igbati ile fi mo.

Ki Olorun se iyawo ni alabiyamo o.

EKO:- Apapo Ijoba Naijiria ti se ikede fun gbogbo awon Osise pe ki awon Osise Ijoba ati awon ile ise awon Oyinbo Onisowo ti nwon da ise sile lati ose to koja pada si enu ise won ni ana tabi ki nwon o padanu ise onje oojo won na.

Ninu iwe ti awon alase Ijoba na ko si ede nwon se alaye pe, Ijoba ko tun le farada ohunti awon osi se na nse lo ju bayi lo ma

Ikede na tun so siwaju pe, ise aje ati owo ti o ti baje ni orile-ede yi ti re koja idaji, Apapo Ijoba ko si tun le fi ara da ohun ti awon osise ose na mo.

Iwe ikede Ijoba na tun se alaye pe, awon osise na ti ba adehun ise won je nipa aiko wa si bi ise won lati nkan bi ose meji wa.

Ikede na ni Ijoba fun gbogbo awon osise ti nwon ko ise won sile ni ojo meji pere lati ro inu won lori ohunti nwon ise sugbon ti nwon ko ba pada si enu ise won lehin ojo meji na, Ijoba yio da won duro, nwon o si gba awon elomiran ropo won.

Ni deede agogo mejila osan ana ni ojo meji ti Ijoba fun awon enia na, sugbon titi di bi ati nkowe yi, awon osise na ko ti pada si enu ise won.

Awon oyinbo onisowo bi U. A. C, P. Z U T. C., J. Allen C. F, A. O. John-Holt ati bebe lo ti fi iwe si ode ni owuro ana pe, awon kilo fun awon osise awon pe, ki gbogbo won o pada si enu ise won ni ojo Eti ti ise ojo kejila osu yi, eniti ko ba si pada ni ojo na (ola) awon yio gba elomiran ropo Oluware,

Sugbon iwe kan ti sese jade ni ale ana lati Odo awon Asiwaju egbe awon Osise pe, enikeni ko gbodo pada si enu ise won.

Iwe na tun so fun awon Osise pe, ki gbogbo won joko sile ki nwon o mase wa si ile ise won ni Owuro yi, aitori ki o ma ba se si ja tabi rogbodiyan larin awon Osise ati Olopa.

Ni gbogbo ile ise kookan ni awon olopa nduro si ti nwon si nso awon ile ise na.

Gbogbo awon idoti ile ti nwon ko jo larin ilu, ko si awon osise ti nwon ko ile na, gbogbo re lo wa larin ilu awon osise ko fo gota ati awon ile iyagbe gbogbo won lo si nrun titi di asiko ti a nkowe yi.

Irohin fi ye wa pe Alaiyeluwa Musediku A d e n i j i Adele Keji Oba Eko ti kesi gbogbo awon Asiwaju egbe osise pe, ki nwon wa ri on ninu Afin on, ki won si so gbogbo ohun ti o ba ndun won lokan fun on.

Agbo wipe Oba Adeniji Adele ti se ileri pe on yio pari oran na fun won loni sugbon o ro gbogbo won ki nwon pada lo si ibi ise

Bi Oba Adeniji Adele keji Oba Eko ba ti pari oran na si, e o ma a gbo ninu iwe irohin wa ni ola.

E Ma a Ka Iwe Irohin Imole Lojojumo

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (11/6/64)